AWỌN OHUN PATAKI
NINU IWE ỌSẸ YI
Ọwọ tẹ awọn onitẹtẹ
Oju iwe 1
Adegoke Adelabu jare
Oju iwe 1
Opin yio de si ijọba Ọpẹ
Oju iwe 2
Kini Itumọ Akukọ Lobo
Oju iwe 3

# IRAWỌ ★ OBOKUN

Ọba Ẹsa-Oke ati Olọtu
Oju iwe 4
Kogajugo şu ọna
Oju iwe 5
Kini Ayirọ ngge kalẹ
Oju iwe 6
Nigeria ta koko pupọ
Oju iwe 7
Ayiloka dagbere
Oju iwe 8

Vol 4 No 164 ILESHA MONDAY NOVEMBER 28 1955 IYE OWO: TỌRO

# AWỌN OLE YIN ASODE LORUN PA: OWỌ TẸ ONITẸTẸ MERIN

## ADEGOKE ADELABU JARE ẸJỌ

Ni ọjọ kerinlelogun osu yi ni Ọlọla Adegoke Adelabu jare ẹjọ kotẹrun tẹ niwaju adajọ agba, Ọlọla ọmọba Adetokunbọ Ademola.

Wọn ti da ẹjọ na lojọ karundọgbọn oşu August ni kotu kekere pe Ọlọla Adegoke Adelabu lọ şẹwọn oşu meji nitoripe o ri kotu ibilẹ ti Ọ'jaba Ibadan fin.

Adajọ agba faramọ ọrọ Ọlọla Dingle Foot Q.C, agbẹjọro Adelabu pe kotu na ko i ti wa nipo ti o fi le ma jẹ kotu gidi lasiko ti wọn ni Adelabu huwa irifin na.

O ni o han ninu iwe tiwọn figbe kotu na kalẹ ati ẹjọ ti wọn to ni kotu kekere pe isọgbe kan şoşo lo ti joko pẹlu adajọ lọjọ na dipo mẹta ti ofin wi.

Adajọ na kọ lati gba kotẹrun Ọgbẹni L. Ade Bello, lori wipe Kotu duro dede ko duro dede o jẹbi gbigba ti wọn ni o gba tiadajọ kotu ibilẹ na leti.

A gbọ pe agbẹjọro Bello ti nwọna lati gba kotẹrun fuu

## AWỌN ỌMỌ'BA CHARLES ATI ANNE



AWỌN ỌMỌ'BA CHARLES ATI ANNE

Wọn bi Ọmọ'ba Charles Philip Arthur George ni ọjọ kerinla ọdun 1948. Wọn bi aburo rẹ Ọmọ'ba Anne Elizabeth Alice Louise ni ọjọ karundogun oşu August 1950. Awọn mejeji ni yio ba iya wọn ọe Nigeria wo ninu oşu kini ọdun to nbọ.

## ỌWỌ TẸ AWỌN ONITẸTẸ

Lati ọpọlọpọ ọjọ ti awọn ọkawe ti nkigbe ninu Irawọ Obokun ni pa nu jamba ti awọn onitẹtẹ ma nse sun awọn ero o n a agbegbe Ijẹsa lapa ni Orita Idominasi ati orun Iyanu Itagun ni Isoja Ibodi.

Nitoribe, ni ọjọ ketalelogun oşu yi, ọwọ tẹ awọn Ọgbẹni Lawrence Ajasetendu ati ẹnikan ahọ pẹlu moto wọn lati ọna Osogbo ni wọn ti awọn onitẹtẹ meji lorita Idominasi ti wọn ma tẹtẹ.

Bi wọn ti duro, ti wọn si nsọ fun awọn onitẹtẹ na pe ko dara ki wọn ma fogbara mu ẹnia ta tẹtẹ ni wọn fa ọbẹ yọ.

Ọpọlọpọ awọn ero ta wa lati igboro Idominasi ni ko jẹ ki awọn onitẹtẹ na gun a wọ n Ọgbẹni na lọbẹ pa.

Lati ibẹ ni wọn ti ran ẹnikan to gun alupupu si Ọlọpa; Igbati ọlọpa de wọn sa, şugbọn, gẹgẹbi a ti gbọ, awọn ọlọpa ri merin mu ninu wọn.

Awọn merin si ti wa ni itimọle.

Kosi oju ogbẹ lara rẹ şugbọn o dabi enipe nşe ni wọn yin lọrun pa.

Iwadi ọrọ na ti wa ni ikamọ ọlọpa.

## OLE PA ŞỌDEŞỌDE

Lowurọ ọjọ karundọgbọn oşu yi ni ọgọnlọgọ enia wọ lọ si ile ti Ọgbẹni T A Babajide ti nra koko lọna Ijebu-Jẹsa lati wo asọde ti ole pa mọju ọjọ na.

Awọn ole na ko koko ti o pọ lọ nibẹ; Wọn de okun mọ asọde na lọna mẹta.

## A TỌRỌ AFORIJI

Ninu Irawọ Obokun ti ọsẹ to kọja, a ripe wọn şe atako Ọgbẹni Adeşulurẹ loju awẹ keje iwe na. O dun wa pupọ pe iru rẹ ni lati şẹlẹ lẹhin igbati a ti şe ikilọ pe wọn ko gbọdọ faye gba iru atako bẹ.

A ti ba awọn ti ọrọ na kan wijọ pupọ. Nitorina a lodi si gbogbo ọrọ to kan Ọgbẹni Adeşulurẹ ninu iwe na, a si tọrọ aforiji nitori inira to ti ni lati fuu u.

(1) ALABOJUTO OLOTU
(2) OLOTU

## BOARD OF DIRECTORS' MEETING.

**The meeting of the Board of Directors, Ijesha Press Ltd. takes place on Tuesday November 29, 1955 at 5 p.m. at the Press workshop premises.**

AGENDA:—

1. **Minutes & Matters arising**
2. **Audit Report**
3. **Business Report**
4. **Certificate of Shares**
5. **General**

## MEETING OF SHARE HOLDERS

**Notice is hereby given that a meeting of the Shareholders of the Ijesha Press Ltd., will be held at Obokungbusi Hall on Tuesday 6th December 1955 5 p.m.**

AGENDA:—

1. **Minutes & Matters arising**
2. **Audit Report**
3. **Press Progress**
4. **General**

Ag. SECRETARY.



ỌGBẸNI ỌKẸ, A. S. P.

O jẹ ọkan ninu awọn ọmọ Ijẹsa to jẹ ọga nibi isẹ Ọlọpa Ijọba Nigeria (Nigerian Police) Lati nkan bi ọsẹ meji lo nde si Ilẹşa fun isimi. Yio de ọpọlọpọ ilu lati lo isimi rẹ ko to bẹrẹ isẹ.

# FA OGBON YO

## ỌGA ONIMOTỌ, PADA NIBITI O DE?
(Lati Ọwọ Otitọ-koro)

Ni ọdun ti a fẹ bọsi lalpẹ yi, gbogbo awọn enia ipinlẹ Iwọ Orun Nigeria yio ni anfani lati dibo yan awọn enia ti yio ṣe ijọba fun ipinlẹ yi,

Ninu ọgọrin enia ti ao dibo yan fun ile iṣofin Ipinlẹ yi, Ijẹṣa yio yan meji. Iṣiṣẹ kini ninu eto idibo ti o nbọ yi ni fifi orukọ silẹ. Enikẹni ti ko ba fi orukọ silẹ ko le ni anfani lati dibo. Gbogbo awọn ti o ni ẹtọ lati fi orukọ silẹ ṣ u g b ọ n ti ọgbọn a-gbọju ko jẹki nwọn fi orukọ wọn silẹ ti sọ ọkan ninu ogun ibi wọn nu.

Awọn meji wo ni Ijẹṣa yio ran lọ sile Iṣofin ni Ibadan lọdun ti o nbọ yi?

Awọn meji ti Ijẹṣa yio ran ni lati jẹ ẹniti ẹkọ wọn to lati lọ sibẹ, ti iwa wọn si tẹ Ijẹṣa lọrun, ki iṣe ẹniti yio tun ma bere lọwọ ẹgbẹ rẹ pe "awe kini nwọn ti wi nipa ọrọ bayi-bayi" Lotọ akoko ko iti de ṣugbọn a ti ri awọn ti o ti nsare kiri bayi, ati ẹniti o tọ ati eyiti ko tọ.

Ọpọlọpọ enia ni o ti wa sọ fun mi pe ọga onimotọ titun nafẹ ki Ijẹṣa ran on lọ si Ibadan. Mo bere pe kini o fẹ lọ ṣe ni Ibadan? O yẹ ki ọmọluwabi mọ iwọn ara rẹ.Ọtọ ni iṣẹ ti owo le ṣe, ọtọ ni iṣe ti ẹkọ ti o jinlẹ le ṣe. Ọgbọn jamba lati fi owo jọ nidi iṣowo ko le wulo nile k iṣofin, lotọ lagbaja ti a nwi yi gbọn ferefere, ṣugbọn ọgbọn jamba ni ọgbọn tirẹ.

Ki a ma gun motọ yale kiri loru-loru, ki a ma fun enia ni ṣẹki ti ko lowo ninu, ki iṣe ọgbọn, jamba ni a npe iru nkan bẹ? Ko daju pe lagbaja yi ni ọrẹ otitọ, bi o ba ni ọrẹ o t i t ọ, ko daju pe o nfi ọrẹ han awọn ọrẹ rẹ, o ni lati jẹ pe awọn ọrẹ rẹ ki i sọ otitọ fun u, tabi pe ara on papa kọ otitọ.

Ẹ jọwọ ẹ ma ṣe jẹ ki a fi owo ba Ijẹṣa jẹ o, gbogbo wa ni a yẹ owo rẹ si, ṣugbọn bi aṣeju ba wọ ọ, Ijẹṣa yio sọ fun u pe ẹnikan ko le fi owo ba gbogbo Ijẹṣa jẹ.

Lotọ ẹgbẹ Akukọ ni gbogbo aiye fẹ dibo fun lati ṣe ijọba titun ti o nbọ, ṣugbọn sibẹ sibẹ bi lagbaja na tilẹ jẹ ọmọ ẹgbẹ Akukọ bi nwọn ba fi sode, Ijẹṣa ko ni dibo fun rara, Ẹgbẹ Akukọ ni awọn enia ti o kun oju iwọn, eo ma gbọ nigbati o ba ya.

Ẹ jọwọ ẹniti o ba mọ oju ọga onimotọ ki o kilọ fun, Ile Iṣofin ni a fẹ yan enia si, ki i ṣe ile ibiti a ti nra koko tabi ekurọ, ki iṣe on ni kan ni a da aiye fun, o ti yawo lẹkan, o ngba owo oṣu lọwọ ijọba, sibẹ-sibẹ o tun npin owo kiri loru loru, o fẹ lọ si Ibadan.

Awe, ibẹ yẹn ga ju ọ lọ. Pada nibiti o de yẹn.



ỌGBẸNI LAWRENCE ỌMỌLE

Ọgbẹni Akindele Ojo darukọ on na gẹgẹbi ẹniti on ni iteriba ati ibọwọ pupọ fun. O bẹ on na pe ki o kilọ fun ẹniti o fẹ ma forukọ rẹ ṣe kundekunde ninu iwe ebibu ti ẹni na nti jade lọsọsẹ. O ni iru iwe bẹ ko dara ni ilẹ Ijẹṣa.

# IRAWO OBOKUN FUN ERINMO

Ẹnikẹni ti o ba fẹ lati ra rawọ Obokun ni Ẹrinmọ ati agbegbe rẹ ki o bere lọdọ Ọgbẹni Samuel O. Ogundele Ọna Ẹffọn No 644 Ẹrinmọ.



ỌGBẸNI I. O AJANAKU

Ninu iwe ọsẹ yi, Ọgbẹni Akindele Ojo sọpe on ni iteriba pupọ fun Ọgbẹni wa yi. Nitorina o bẹ pe ki o kilọ fun ẹniti o fẹ ma forukọ rẹ ṣe kundekunde ninu iwe ebibu ti ẹni na ntẹ jade lọfẹlọfẹ lọsọsẹ.

## OPIN FẸ DE SI IJOBA ỌLỌPẸ
(Lati Ọwọ Benson Adegbọla AN 12 Igbaye).

Olotu, jọwọ gbami laye diẹ lati ṣe alaye fun awọn ọmọ Iwọ Orun pe opin Ijọba awọn Ọlọpẹ tide. Mo fẹ ki gbogbo enia ma fi ọkan balọ bi nkan gbogbo ti nlọ si bayi pe ẹsẹ awọn Ọlọpẹ nmi ni ilẹ. Gbogbo awọn Aṣaju wọn ti nsa kuro nibẹ, ti wọn nwọ ẹgbẹ Alakukọ.

Mo dupẹ lọwọ awọn to nronu wọn lasiko yi, ti wọn nfi ẹgbẹ na silẹ bayi. Tani o le mu omi to ẹniti o ku sinu omi? Owe agba ni o.

Ẹ wo Omilabu Ghandi ni Ibadan, on ni akọwe eleto Ọlọpẹ, on si ṣe pataki larin wọn, ṣugbọn sibẹsibẹ, o ronu rẹ, o fi ẹgbẹ na silẹ.

Bẹni Ọgbẹni Ladipọ, awọn wọnyi jẹ Oguna gbongbo ninu ẹgbẹ Ọlọpẹ.

Ẹnyin ọmọ Ijẹṣa, ẹ ma jẹki ẹnikan fowo tan yin. Ṣe ẹgbẹ ti gbogbo enia ti nkọ silẹ bayi lasiko ti ọjọ kusi dẹdẹ ti ọjọ ẹsin awọn Ọlọpẹ sun mọ tosi yi, ni eo tẹri si? Ẹnyin ti ẹ fi ọmọ si ilewe ọpẹ, ẹ ko mura silẹ lasiko yio nitori awọn ọlọpẹ ti na owo ti ao fi tọ awọn ọmọ wọnyi tan. Ẹ o si ri nkan ti wọn fẹ gbe jade lọdun to mbọ. Ọna ti a le fi gba ara wa lọwọ wọn nipe ki awa ọmọ Ijẹṣa ti orukọ silẹ lasiko yi ki a le ni ida lọwọ lati jagun.

Mo ngbọ pe owo ni awọn ọlọpẹ yio fi di ibo ilẹ Ijẹṣa, Njẹ ẹnyin ọmọ Ijẹṣa, ṣe ẹnyin na le ta ogun yin tori owo gẹgẹ bi Esau tiṣe ta ogun ọjọ ibi rẹ nitori onjẹ? Owo tobi, ṣugbọn nkan ole ni. Ọbẹ ti Ọlọpẹ se kalẹ, wọn ti fi jẹun tan. Ẹnyin ti nwọn ba tan wọ ẹgbẹ bayi ni yio fọ isasun ati awo ti nwọn fi jẹun.

Ki gbogbo wa ronu wo bayi ki a tun tete tẹle ẹni ti o ran ni ni nkan ọbẹ, ti wọn ti lọ ata silẹ, ti wọn fẹ ṣe ọbẹ tiwọn bayi. Ẹ maṣe jẹki a pẹ de ọdọ wọn ki ọbẹ awọn na ma ba tan ki a to de ibẹ.

Mo fi da yin loju pe ọna Ekiti ti wọn gbẹkẹle, Akukọ ni yio wọle nibẹ. Awọn Ijẹbu papa ti nronu wọn wo bayi ṣugbọn ẹnyin Ijẹṣa ẹ maṣe jẹki ọpẹ tan yin jẹ o.

Akukọ ni yio gba agi ọdun ti mbọ lọwọ Ọlọpẹ ẹ fi orukọ silẹ lasiko yi o.

# AKIYESI PATAKI

Eyi ni lati sọ fun gbogbo awọn to nkọwe sinu Irawọ Obokun pe lati asiko yi lọ a ko ni faye gba iwe ẹnikẹni ti ṣe atako ẹnikẹni tabi ẹgbẹkẹgbẹ. Ṣugbọn aye wa fun ẹnikẹni lati sọrọ lori eto ati iṣẹ ẹgbẹ tirẹ laipa ẹnikẹni lara:

ALABOJUTO

# IROHIN LATI AGBEGBE

IJEBU-JẸṢA

## ONIFADE Ṣ'.JỌYỌ OYE RẸ

Ni ọjọ kẹrinla oṣu yi ni Ọgbẹni Onifade Ajarogbodu se ajọyọ Oyẹ rẹ ni Ijebu-Jesa.

Ni nkan bi ọsẹ meji ṣaju ọjọ na ni on awọn ẹbi ati awọn ọrẹ rẹ ti nmura silẹ fun eto ajọyọ na.

Lati ọjọ kẹrinla, ọjọ kẹtala oṣu na ni eto ti nlọ ni ile oloye titun na lẹmu. Siga, ọtin ati ọpọlọpọ ohun jijẹ ko niyẹ.

Bi ilẹ ọjọ ajọyọ ti nmọ ni okiki odo iyan ti nro tokintokin ninu ọpọlọpọ agbo ile to wa ni ayipo ile Onifade.

Ajẹti ni awọn to wa sibi aṣeyẹ na jẹ, bẹni wọn mu amusẹku ohun mimu pẹlu.

Diẹ ninu awọn to wa sibẹ ni awọn Ọgbẹni Oladunjoye Animọ, M. O. Arowoṣẹgbọ, M. O. Arogundiyan, Oladele Ekemọde, S. Debọ Sẹriki, Alice Ige, Ester Ilọri, Amos Ọsanlana ati awọn miran

IBODI

## ẸLẸJỌ FẸSUN KAN ADAJỌ

Ni ọjọ kerindinlogun oṣu yi ni Ọgbẹni Abrahan Oni duro ni Kotu lati wa dahun si ẹsun tawọn fi kan pe kosan owori tọdun to koja.

O sọ fun kotu na pe Lọyin Igila, ẹniti o jẹ ọkan ninu awọn to gbowori tọdun to kọja ni on san fun. O ni lati igbana ni on ti nreti iwe ẹri ti on sọpe ko ba on gba.

Ọgbẹni na tọka pe Ọlọja Ibodi to jẹ alaga kotu na ni ẹlẹri on. Laijẹki Ọgbẹni na tabi ki ẹleri sọrọ, Lọyin Igila ẹniti o jẹ ọkan ninu awọn adajọ ibẹ, to si jẹ ẹniti wọn sọpe awọn ti sanwo fun, da ẹjọ na pe Abrahan Oni jẹbi, nitorina ko san poun kan owo faini.

Lọjọ kanna niwọn gbọ ẹjọ Ọgbẹni John Onigbogi ti Ita-Ọsun. Ọgbẹni na ko wa ṣugbọn o ran ọmọde kan lati jẹjọ fun u.

Nwọn ;i on na jẹbi wọn si faini rẹ ni poun kan.

OṢOGBO

## WOLI TẸLẸDALAṢẸ ṢE IKOMỌ JADE

Ni ọjọ kẹsan oṣu yi ni Ọlọrun fi Ọmọbirin kan rubutu ta Woli James Tẹlẹdalaṣẹ ti 156 Station Road Oṣogbo lọrẹ.

Ni ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi ni wọn sọ ọmọ na loruko. Ni ile ijọsin ẹgbẹ Kerubu ati Serafu ni wọn sọ ọmọ na loruko.

Gbogbo ẹsẹ awọn aṣaju Serafu ati Kerubu pẹlu awọn woli ati awọn ọmọ ẹgbẹ lo pe sibi aṣeyẹ na ti wọn ti bẹrẹ lati agogo mẹrin irọlẹ si mẹsan alẹ.

Orukọ ti wọn sọ ọmọ na ni Ester Ọlanikẹ Oluwasanu Atọkẹ Ọladimeji. Elizabeth Oni ni iya ọmọ titun na.

Diẹ ninu awọn pataki to wa sibi aṣeyẹ na ni Woli J. Ajakaiye, I. Isaac, Oluṣọ Agutan J.B Awoṣoga, Apostle E. O Ogun, Woli Alice, Adebimpe, Marian Ifẹ.

Alagba J. Owobọrọdẹ, Josiah, Fadiora ati awọn miran pẹlu Titus Oludini.

Ki Oluwa ki o fi rere kari gbogbo wa o. Amin.

## ỌNA ETIỌNI SI IGANGAN NFẸ ABOJUTO

(Lati Ọwọ S. O Clarkson Obembe).

Mo bẹ Olotu Irawọ Obokun lati gbami laye lati sọ iba ọrọ mi kekere yi sinu Irawọ Obokun Oloyin momọ ọsẹ yi.

O dun mi pupọ lati sọpe Ijẹṣa ko ni ọna motọ to dara, Ọna Etiọni ti ijọba ilẹ Ijẹṣa ti na ọpọlọpọ owo si, ti wọn si ti na ara si ti bajẹ kalẹ lai tunṣe bayi.

Lotọ ni awọn ijọba yio ma rope ọna di meji si Etiọni; ekini ni eyi to ba Odogbo lọ, ati eyi to ba Igangan lọ. Nko rope yio jẹ nkan to buruju ti ijọba ba ṣe awọn ọna mejeji yi dada.

Anfani ilẹ Ijẹṣa lo ma jẹ ti ọna na bale lọ si Okegbo tara lati Ileṣa. Emi papa ro pe awọn ara Etiọni papa ko fẹ ki ọna meji jade si arin igboro ilu wọn.

Nitorina mo bẹ ẹnyin Ijọba ilẹ Ijẹṣa lati bawa boju to ọna na Ọna na si jẹ pataki ninu ọna motọ ti Ijẹṣa ni. Anfani gbogbo awa Ijẹṣa lasi ma jẹ ti ọna na ba dara.

Ẹ jọwọ, ẹnyin Ijọba ilẹ Ijẹṣa, ẹ bani boju to ọna to bẹrẹ lati Ileṣa ba Igangan lọ.

Ọlọrun Olodumare a ran yin lọwọ. Obokun a gbe yin o.

IPETU-JẸṢA

## IKORE AWỌN ỌMỌDE LARINRIN

Irohin ko to afojuba ni ọjọ ti awọn ọmọde ṣe Ajọdun Ikore ni St Mary's Church Ipetu ni ọjọ 6 oṣu yi.

Alaga S. T Ayọtunde loṣe iwaṣn lọjọ na. Ọrọ iyanju ọjọ na ti wọn fi ba awọn ọmọde sọrọ, ni Oniwasd 12 ẹsẹ 1 Ranti Ẹlẹda rẹ ni igba ewe rẹ.

Ọgbẹni M. M Akinmọladun, Oga ile iwe ni o ṣe alakoso Ikore yi. Awọn ti o ran lọwọ ni Ogbẹni M. O Aribilọla, J A Aiyegbusi, Omidan, Ọlawumi Erinlẹ.

Owo ti wọn kojọ lọjọ na ju ti ọdun to kọja nilọpo mẹta,

Ni ọjọ Monday, 7 oṣu yi, niwọn ta ọja Bazaar.

Ọgbẹni A Oyeson ọkan ninu awọn Ijọ yi, ti wọn si ti kọwe ni ilewe yi ri ni o ti Oṣogbo wa nibi ti o ti nṣe, lo wa ṣe Alaga ọja Ikore na.

Ọgbẹni Kọlawọle Fapohunda, H. M Apostolic School ni olutaja ọjọ yi. Wọn nawo pupọ lọjọ yi lati ra ọja ikore.



OGBẸNI LAWRENCE AMOKEODO

Ni ọjọ ketalelogun oṣu yi ni on ati ẹnikan ba awọn onitẹtẹ ọna Idominasi nibi tẹtẹ wọn. Wọn ni dic loku ki awọn onitẹtẹ na gun wọn lọbẹ. A gbọ pe wọn ti ko mẹrin timọle ninu wọn.

# Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu "IRAWO ỌBOKUN"

OJU EWE KINI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 8s. | fun inṣi kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. 6s. | " " " |
| Igba | 26—52 | 7s. | " " " |

OJU EWE KEJI

| | | | |
|---|---|---|---|
| igba | 1—12 | 5s | fun insi kan |
| igba | 13—25 | 4s. 6d. | " " " |
| Igba | 26—52 | 4s. | " " " |

OJU EWE KẸTA

| | | | |
|---|---|---|---|
| gba | 1—12 | 7s. 6d. | fun inṣi kan |
| Igba | 13—25 | 7s. " | " " |
| Igba | 26—52 | 6s. 6d. | " " " |

OJU EWE KẸJỌ

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 6s. | fun inṣi kan |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | " " |
| Igba | 26—52 | 5s. | " " " |

OJU EWE 4, 5, 6, ATI 7 JE OWO KANNA PẸLU TI OJU EWE KEJI.

